139 *Kọ́ Wọn Kí Wọ́n Lè Dúró Gbọn-in*

(Mátíù 28:19, 20)

1. **Báa ṣé ńkọ́ àgùntàn Jèhófà**
   À ńláyọ̀ pé wọ́n ńdàgbà.
   À ńrọ́wọ́ rẹ̀ bó ṣe ńdarí wọn
   Wọ́n ńsòótọ́ di tara wọn.

   (***ÈGBÈ***)
   Jèhófà, gbọ́ àdúrà wa
   Jọ̀ọ́ f'àbò rẹ bò wọ́n Baba.
   Lórúkọ Jésù, a bẹ̀ ọ́: Kí wọ́n yege;
   Kí gbogbo wọn lè dúró gbọn-in.

2. **'Joojúmọ́ là ńgbàdúrà fún wọn,**
   Kí 'gbàgbọ́ wọn má ṣe yẹ̀.
   À ńkọ́ wọn, a sì ń ṣìkẹ́ wọn;
   Wọ́n ńlókun, Jáà ńbù kún wọn.
   (***Ègbè***)

3. **Jọ̀ọ́ jẹ́ kí wọ́n máa gbẹ́kẹ̀ lé ọ,**
   Ìwọ àti Ọmọ rẹ.
   Pẹ̀lú 'faradà àtìgbọ̀ràn,
   Kí wọ́n lè jogún ìyè.
   (***Ègbè***)

(Tún wo Lúùkù 6:48; Ìṣe 5:42; Fílí. 4:1.)

© 2015 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania